# IROHIN IMỌLẸ

MỌLE ORE AIYE TENI GROGBO LAWA

No 1,572 MONDAY NOVEMBER 29, 1965 (2D)

## IGI WO PA ỌKUNRIN KAN

KABBA:- Ni opin ọsẹ to kọja lọ yi ni irohin kan de ọwọ wa pe igi nla kan o pa ọkunrin kan ni abuleko kan ti a npe ni Abejukolo ni ọba Igala ẹkun Kabba Ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria eyiti o jẹ wipe bi ọkunrin na ti nge igi nla na ni o ba wo lulẹ lojiji ti o si wo pa ọkunrin na.

Irohin fi ye wa pe bi ọkunrin na ti kilọ fun ọmọ rẹ ti nwọn jijọ lọ sinu oko ibiti ọkunrin na ti lọ ge igi na pe ki ọmọ on kuro ni agbegbe ibiti on ti nge igi nla na. Ṣugbọn bi ọkunrin na ti nsọ fun ọmọ rẹ ni igi nla na ba wo lulẹ ni ojiji eyiti o si wo lu ọkunrin na ti o si pa a.

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn enia ti ngbe ni ilu na ti nwọn gbọ ariwo ẹkun ọmọ ọkunrin ba tete lọ sinu igbo na lati lọ wo ohunti o ṣẹlẹ si ọmọ na. Nigbati awọn enia na de inu igbo na ni nwọn ba ri igi nla ti o wo lulẹ eyiti o wo lu ọkunrin na ti nwọn si gbe oku ọkunrin na lọ si ilu wọn lati lọ sinku ọkunrin na.

Ninu irohin ti a tun ri gbọ lati ilu Kabba fi ye wa pe enia mẹta tun padanu ẹmi wọn ninu ijamba mọto kan to ṣẹlẹ ni oju ọna eyiti o jẹ wipe mọto akero na si lọ kọlu kẹrẹni nla kan ti o si dojubolẹ eyiti awọn enia mẹta si ku ninu awọn enia to wa ninu mọto okero na.

# ALHAJI ADEGBENRO LỌ RI GOMINA IWỌ ORUN

IBADAN:- Alhaji D. S. Adegbenro, Adele Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre, ati Asiwaju ẹgbẹ Ajumọsepọ (UPGA) pẹlu awọn sarakisatakì ninu awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ ti lọ ri Ọlọla Ọdẹlẹye Fadahunsi, Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun ni opin ọsẹ ti o kọja lọ yi lori gbogbo awọn nkan ti nṣẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria



**Alhaji D. S. Adegbenro**
ADELE OLORI ẸGBẸ AFẸNIFẸRE

Gẹgẹbi Irohin ti a ri gbọ ninu ile iṣẹ wa ni ale ana ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kejidinlọgbọn oṣu yi, a gbọ wipe, wakati mẹrin gbako ni awọn ọmọ ẹgbẹ na fi sọrọ pẹlu Ọlọla Ọdẹlẹye Fadahunsi ninu ile rẹ.

Ṣugbọn bi awọn enia ti se sọrọ wọn na to, nigbati nwọn yio fi pari ipade wọn na ni gbogbo iwaju ile ati gbangba ode na ti kunsoso fun awọn enia ti nwọn ti gbọ wipe awọn enia na wa sọrọ pẹlu Ọlọla Ọdẹlẹye Fadahunsi ti nwọn si fẹ mọ ohunti nwọn yio sọrọ le lori ati ibiti nwọn yio , ari ọrọ na si.

Ṣugbọn nigbati awọn enia na wọle lọ ba Ọlọla Fadahunsi tan, awọn Ọlọpa ko jẹki ẹnikankan wọle ninu gbogbo awọn enia ti nwọn duro si ode na lati lọ gbọ ọrọ ti nwọn fẹ sọ.

Ṣugbọn nkan ninu awọn ti nwọn mọ ninu awọn ohunti nwọn fẹ sọ ninu iru ipade bayi ṣe alaye fun wa wipe, ọrọ ti nwọn sọ ni nipa bi gbogbo nkan ti ṣe nlọ ni Ipinlẹ yi nisisiyi ati ọna ti nwọn le gba ti gbogbo awọn nkan ti ko dara to ninu ibo ti nwọn di kọja lọ yi yio fi dara.

Nigbati awọn enia na de ọdọ Gomina na lori iwe ti Ọgbẹni Eyo Esua ko sii nipa abayori ibo ti nwọn di kọja lọ yi, Alhaji Adegbenro fi iwe na han Gomina gẹgẹbi ohunti Gomina na ti nṣe tẹlẹ wipe Ọgbẹni Esua lo kọwe si on ki on to pe Oloye Akintọla lati wa ṣe Ijọba.

Awọn enia na tun ṣe alaye ninu iwe ti Ọgbẹni Esua ko si Gomina na wipe Ọgbẹni Esua ti ṣe alaye ninu iwe na wipe on paapa ko fi aramọ ọna ti awọn akowe eto ibo gba se eto ibo ti o kọja lọ yi, bẹni on ko si kowe si enikanka ni pari ibo na wipe ki nwọn wa ṣe Ijọba gẹgẹbi ọrọ ti on ngbọ ti awọn enia kan nsọ kakiri lati ọjọ ti ibo na ti pari.

Ọkan ninu awọn enia ti nwọn jijọ wa ninu ipade ti nwọn se ni ọjọ na ṣe alaye fun Oniwe Irohin wa ni Ibadan wipe bi awọn enia na ti se sọrọ to ati bi nwọn si ti pẹ ninu ipade na to, gbogbo awọn nkan ti nwọn sọrọ le lori na lo tẹ awọn enia ẹgbẹ mejeji lọrun ti nwọn wa si ibi ipade ọjọ na.

A tun gbọ pẹlu wipe nigbati ipade na pari, nse ni gbogbo awọn enia ti nwọn ba Alhaji Adegbenro lọ si ọdọ Gomina na fi ẹrin jade ti gbogbo nwọn si nrin ẹrin bọ bi nwọn ti njade bọ lẹhin ipade na ninu ile Gomina.

Ṣugbọn nigbati awọn enia ti nwọn duro si ode ri awọn enia na nigbati nwọn njade bọ nwọn sare lọ pade wọn ni oju ọna. Awọn Oniwe Irohin bere ọrọ lọdọ awọn enia na ṣugbọn nwọn sọ wipe.

"Ẹ fi ara balẹ, gbogbo ọrọ ti a lọ sọ na ni ẹ o ma a gbọ laipẹ yi."

Onirohin wa kan ran wa leti wipe, ni



**Ọlọla Fadahunsi**
Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun

ninu ọsẹ ti o kọja lọ yi ni Alhaji Adegbenro lọ ri Alhaji Abubakar Tiṣẹ, Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria lori ọrọ Ipinlẹ Iwọ Orun yi kanna ti awọn mejeji si jijọ sọrọ lori ọrọ yi kanna, ṣugbọn nigbati nwọn pari ipade wọn ọjọ na nwọn ko ba ẹnikankan sọrọ lori ohunti awọn mejeji jijọ sọrọ le lori nigbati nwọn pari ipade ọjọ na.

Ṣugbọn Onirohin wa kan sọ wipe lati ọjọ ti nwọn ti pari ibo Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni awọn enia Ipinlẹ ti bẹrẹsi maa pa ara wọn bi igbati nwọn ba npa ẹran Ileya ti ko si alafia ni Ipinlẹ na titi di igbati a fi nkọwe yi lọwọ.

Awọn enia ti nwọn ti pa ninu rogbodiyan Ipinlẹ na nisiyi ti le ogorin gẹgẹbi isiro ti awọn enia na nṣe.

A tun gbọ pẹlu wipe awọn ile ti nwọn ti sun ati awọn mọto ti nwọn ti bajẹ kọ tifi ẹnu sọ.

A tun gbọ pẹlu wipe awọn si tun npa ara wọn ni awọn agbegbe kan ni Ipinlẹ Iwọ Orun papajulọ ni agbegbe Ekiti, Ọwọ ati Mushin.

Ninu ọsẹ ti o kọja lọ yi ni awọn olọpa yinbọn pa Direba mọto kan nigbati onimọto na nlọ si ibiti yio gbe ko awọn ero ti o fẹ ko lọ si Agege ni owurọ ọjọ na

# IRANTI AJỌDUN ỌDUN KEJILELOGUN OMINIRA

Ni deede agogo mẹjọ kutukutu owuro ana ọjọ Aiku ti iṣe ojọ kejidinlogbon oṣu yi ni Irohin kan de si Ile iṣẹ Iwe Irohin wa lati ile iṣẹ Asoju Ijọba Orilẹ ede Ilẹ Yugoslavia ni Naijiria ni nomba 5, Alhaji Ribadu Road, wide, Ijọba orile ede na yio ṣe iranti Ajọdun Ajọyọ ọkun kejilelogun ti Ijọba Orilẹ ede Yugoslavia gba Ominira ti nwọn si bọ kuro ni oko ẹru.

Gẹgẹbi Irohin ti o to WA lọwọ ninu Ile iṣẹ wa ni owurọ ana, a gbọ wipe ni ojo kokandinlogbon oṣu kokanla ọdun 1943 ni Ijọba ori'ẹ ede na gba Om'nira ti nwọn si bọ kuro ni oko ẹru kuro ni abẹ awọn orilẹ ede ajoji ti wọn ti npase le wọn lori lati ẹhin wa

Ọgbẹni Orazan Mateljak iṣe akowe eto Irohin fun Asoju Ijọba Orilẹ ede na ni Naijiria fi ye wa ni ana wipe, o ti le ni ẹgbẹrin enia (800) ti awọn enia Orilẹ ede na ni Naijiria ti fi iwe ipe ranṣẹ si lati wa ba wọn yọ ayọ Iranti Ajọyọ Ajodun Ominira ti awọn enia na yio ṣe ni ola

Irohin na ti a ri gbo ni alẹ ana tun ṣe alaye siwaju ninu oro rẹ wipe ni deede agogo mẹsan alẹ ni nwon yio bẹrẹ ayẹyẹ ti nwon lẹ ṣe fun iranti Ominira na ni ola awon yio si pari gbogbo eto na ni nkan bi agogo mẹsan alẹ ni ojo kanna.

Ọkan ninu awọn enia na tun ṣe alaye fun awọn oniwe irohin wa pẹlu wipe awọn ọlọpa orilẹ ede Naijiria ni wọn yio lọ lu ilu wọn ni ibẹ ni alẹ ola lati fi da gbogbo awọn enia ti nwon ti fi iwe ipe ranṣẹ si.

A tun gbọ pẹlu wipe gbogbo awọn Olotu iwe irohin ni nwọn ti fi iwe ipe ranṣẹ si pe ki nwon wa ba awọn yọ ayọ iranti ọdun Ominira ti nwọn fẹ ṣe ni ọla na pẹlu.

Irohin fi ye wa wipe Ijọba Ọlọba ni awọn enia orilẹ ede Yugoslavia ti nlo ri nigbakan lati ẹhin wa ṣugbọn nigbati awọn enia orilẹ ede na tigba Ominira tan niwọn ba ti yi Ijọba wọn pada si Ijọba ti ko fi ti Ọba ṣe tabi Ijọba ti nwọn ko ni Ọba

Irohin natun ṣe alayẹ fun wa siwaju pẹlu wipe awọn enia orilẹ ede Yugoslavia ko mọ tẹlẹ wipe awọn onla kan nbọ wa ba wọn ja ogun ni nu ogun ti nwọn ja kọja lọ yi ṣugbọn nigbati ogun na bẹrẹ ti awọn ọta si ti de tan ni nwọn ba mura were ti awọn na si mura ogun laiko ro tẹlẹ ni gbogbo awọn enia na lọkunrin ati lobinrin ba mura ti gbogbo wọn si lọ si oju ogun lati lọ gba orilẹ ede wọn silẹ lọwọ awọn ota ti nwọn nfẹ gba Orilẹ ede won nigbana.



Ọlola Josip Broz-Tito
Olori Ijọba Yugoslavia

Ṣugbọn nigbati awọn enia ri nigbana wipe ogun bere ti awọn ara ilu ko si mo ohunti nwọn le se ni nwọn ba yara tete pe ipade Parawọ kan ninu eyiti gbogbo awọn ọmọ Ile Igbimọ Asofin Ijọba orilẹ ede na tete se ipade kiakia ki nwọn le ba mọ ọna ti nwọn yio gbe nkan na gba nigbana, ki awọn ota ma ba siko ilu wọn lọ nigbana.

Lẹẹkẹsẹ ti nwọn pe ipade na ni gbogbo awọn ti nwọn iṣe ọmọ Ile Igbimo Asofin Ijoba orilẹ ede na nigbana ati awọn ti nwọn ki iṣe omo Ile Igbimo Asofin nigbana ti parojo ti ese gbogbo wọn si pe samu samu sinu Ile Igbimo Asofin Ijoba orilẹ ede na ni ojo yi.

Ninu awọn to wa si inu Ile Igbimọ na ni ọjọ na ti nwọn ki iṣe ọmọ Ile Igbimọ na ni ọjọ na ni awọn Ọkunrin, awọn Obinrin, awọn Dọkita, awon Loya awọn Sọja, Ọlọpa, awon agbẹ, awọn ọmọ Ile iwe ti nwọn ko ti jade.

Awọn ọmọ Ile ẹkọ giga awọn ọmọ Ile ẹkọ Unifasiti awọn Oniwasu, awọn oniṣẹ Ọlọrun, ati oniruru awọn enia miran ti a ko tun le mẹnu sọ lọ ninu iwe wa yi.

Irohin na tun ṣe alaye wipe lẹhinti awọn ọmọ Ile Igbimo na ti pari ipade wọn tan ni ọjọ na ni awọn enia na ba jade gẹgẹbi ipinnu awọn wipe ki gbogbo awọn enia Ilu lọkunrin ati l'Obinrin jade lọ si oju ogun ki nwọn si lọ ja Ija na gẹgẹbi o ba ti ṣe to ati bi o ba ti ṣe yẹ, ki awon ota ma ba ṣe le ni anfani lati le gba ilu wọn lọwọ won nigbana.

Ọpọlọpọ awọn enia ni nwon nki i kankiri bi aguntan ti ko ni Oluṣọ larin ilu ṣugbon fun nkan bi ojo mẹwa ni awọn enia na ko fi le sun inu ile won ti nwon nkiri ode kaakiri.

Nitoriti awọn enia na ti nṣe ba wonyi, awon miran bọ si ọwọ awon ota ti won ti nduro de won tẹlẹ larin ilu won, nitoripe awọn miran ti gba ona eburu wo inu ilu wọn ki awọn ara ilu na to fura wipe awọn ota ti wo ilu wọn na.

Ni asiko yi kanna ni awọn enia na gba wipe awọn ko tun ni ni Ijọba ti o ni Ọba kan gẹgẹbi olori mọ, ṣugbon ki awọn ni Ijoba ti yio ni Ọga ogun kan gẹgẹbi Olori ilu won ti yio si maa dari gbogbo ohunti awon enia inu ilu na ba fẹ lati ṣe.

Irohin na tun se alaye siwaju wipe gbogbo awọn enia nani wọn gba nigbana wipe awọn fi aramọ wipe ki awọn ni olori kan ti yio maa se adari awọn dipo Ọba ti awọn enia inu ilu na ni tẹlẹ ri lati ẹhin wa

Ọlọla Josid Broz-Tito ẹni ti iṣe olori Ijọba orilẹ ede Yugoslavia nisisiyi losiogun ni gbana ti osi ba awọn ọta orilẹ ede wọn nigbana ja lo ju ogun

Ogun igbana ni ogun tio bere ninu ọdun 1939 ti osi pari ninu ọdun 1945 kigbo gbo awọn nkan to lo sile nigbana ti gbogbo nkan si tun pada bosi ipo rẹ nisiyi

Ọlọla Broz Tito, jẹ ọkan ninu awọn ọga ologun igbana ti nwon fi ẹmi wọn jin iku wipe ki yio ṣi ohunti yo gba orilẹ ede awọn lowo awọn nigbati ẹmi awọn ba si wa awọn ko ni ya oju awọn silẹ ki ẹnikan wa ta omi ota si awọn ni oju

Ore ti a nṣe fun nyin ni oni yi je ohunto ti ṣelẹ ninu ọdun 1943 ṣugbon ẹo tun maa gbọ itan igbesi aye ọlọla Jesip Bros Tito Olori ile Yugoslavia lẹ ipe yi ninu iwe Irohin wa lati tun rawọn aworan re nigbati o wa ni oju ogun pelu awọn ọta ti nwọn nfe pa ilu wọn run ni gbana

Gegẹbi alaye ti awọn Ala sọ asoju ijọba orilẹ ede na ni Naijiria ṣe fun awọn Oni we Irohin ni ana ninu ipabe awon oniwe irohin t'ọlọ la K. rapandza Aṣoju Ijọba orile ede Yugoslavia ni Nai jiria ṣe ninu ile iṣẹ re niowuro ana ni nọmba 5, Alhaji Ribadu Road Ikoyi o ṣefun gbogbo awọn enia na wipe nigbati awon bolu wo ẹhin awọn ti awọn si run ranti gbogbo awọn nkan ti o ti ṣẹle ni awon as ko wonyi awon ilogo fun Ọlorun oba ni ote Ọrun pe awon na ni

WO OJU EWE KARUN

## Iwe si Olotu Irohin Imole

OLOTU IRAWONGBOSE

## Mo Ki Odo Egbe Afenifere Ward H 1

Mba sope bi Alagba ba le gba mi ni aye ranye yi ninu iwe nyin alaka gbadun lati kan sara si awon odo egbe Afenifere ti ekun Ward H1 fun gbigba oro si awon agba lenu loni didi Ibo fun Alhaji Imoru ni ojo Idibo ti Ijoba Ibile Ilu Eko, ti o koja lo yi.

Inu mi dun pupo nigbati awon odo yi gba oro agba ti nwon si yowo ninu ati yan alatako miran sile gegebi Asoju ti ko fi ara mo egbe Olope ti o si fe tako Asoju egbe Afenifere Alhaji O. J Imoru

Mo ki gbogbo awon ti o je koko ninu awon ti o gba oro si awon agba lenu ti nwon si sise fun Asoju egbe Olope Alhaji Imoru ti o fi wole. Iyi nlanla ni o je fun Ward H 1. pe a ko gbaye fun egbe Olowo ati Alakuko lati wole ni ekun yi.

Mo ki gbogbo omo Afenifere ni Ward H 1. e seun Oluwa yio wa pelu enikankan wa o. A ko ni se ti o,

Ki nto pari iwe mi yi, mo ni lati ki awon enia jankanjankan wonyi ni ekun Ward H 1, fun wahala won ni ojo idibo na ati ipa ti nwon sa fun Councilor wa awon bi Ogbeni Osun, Ogbeni Phillip, L. A. Balogun, S. A. Saunmi, R. A. Balogun ti ise akowe egbe Afenifere fun ekun na ati be be lo, mo ki yin e Seun o, e ku ise o. Oluwa yio ma ran nyin lowo o

Emi ni
Latifu Babalola
EKO

## A nfe Aworan Baba Eso

Olotu:- Inu mi yio dun bi eoa le gba mi ni aye die inu iwe nyin to kun fun ogbon ati oye lati kesi ogbeni Eso ti ama nri itan eyiti o je ti igba lailai k n lati owo re ki o jeki ari aworan on ninu iwe irohin Imole nigbati aba ti ri itan egbe Eso ka.

Mo ro pe o to e meta ti awon onkawe irohin Imole ti ma nko oro nipa ti awora ogbeni Eso eyiti nwon ma nbere pe awon fe ri aworan re ninu iwe itan ti oba sinu iwe irohin imole

Inu awa onkawe Irohin yiodun bi olotu iwe irohin imole ba le ba wa so fun ogbeni Eso ki o jeki a tete ri aworan re ninu iwe Irohin Imole eyiti a ti nfe ri lati nkan bi osu die sehin

Mo dupe pupo Olorun fun ayet egba mi oko oba ko ni sa nyin lese o ajinde yio ma je fun nyin o

Emi ni
James Adelana
Apapa Ajegunle

## Ijoba ko ranti ilu Olorunjare

Olotu nba sope bi eba le gba mi ni aye rampe ninu iwe yin oloyin momo lati kesi Ijoba ipinle Aruwa ile Naijiria lati lo ipo re rere ki nwon le ba wa tun awon oju ona ilu Olorunjare se ni asiko

Lati odun pipe ni Ijoba ipinle A ruwa koti ya si ilu wa mo rara ti nwon si ntun awon ilu miran paapa awon ilu ti ko tobi to ilu wa.

Be si ilu Olorunjare ko kere rara ninu awon ilu ti o wa ni ipinle Aruwa ati pe oju ona ilu nasi yato pupo si awon oju ona ilu miran to wa ni ipinle Ariwa ile Naijiria.

Bi enia ba rin oju ona na, olu ware yio ri pe, ko dara to, ati baje fun rinrin osi tun lewu pa po fun awon onimoto iabi rin pe lu.

Inu wa yio dun pupo bi Ijoba Ariwa bale se anu wa lati tete mu oju to oju ona na ni asiko

Olotu mo dupe fun yin ti e gba mi

Emi ni
R. O. Adisa
OLORUNJARE

## IWE KOSEMANI NI EYI

IWE ITOSE OHUN GBOGBO
NINU ODU MERINDINLOGUN

Iwe yi kun fun Asotele ati wipe, yio din o lowo 'YEMIWO" ku, nitoripe iwo na yio le ma da se AYEWO fun ara re

"KOSEMANI" ni iwe na, 2/6d pere ni a nta Postage 9d tete lo ra tire ko to tan

FI OWO RANSE SI -
ESAN KOGBOGUN SERVICE
8, Idumagbo Avenue,
LAGOS NIGERIA
(Leti Oja Jankara L'Eko.

---

GBOGBO ARA ILU NKO ORIN IYIN ATI A NIPA **DYNAMIREN** TONIKI

ALE-BI-ALE Egbogi Toniki amonu tilun ti gbogbo ara ilu Eko ati jakejado Naijiria mo daju fun Akragbara ati Ajebidan ise lara Agbalagba Okunrin gbogbo.



Bi are ara ba nmu o, nigbakugba fun wahala tabi ise sise ti o ko le jeun dara dara, tabi ki o male sun da da de okan Lasan tabi awon saa ara re gbogbo ki eefun daradara ti Emi Breath inu ko ba kunle daradara won ise tabi wahala sise tabi inu awon ailera gbogbo nyin ti ojo ori (age) ba ti koja ogbon odun si adori tabi jube lo mo daju pe DYNAMIREN ni egbogi ti o nfe lari so ara di otun pafapata inu re a jolo eran ara re ti o ti hunjo yio bi yabo dada Ara re yio gbe karkan ni gbakugba yio sao pelu igo baba durode o iyen d jb

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palm Church Street Lagos
Phone.- 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)
LAGOS

---

## EGBOGI JEDIJEDI

BERE FUN EGBOGI

## "CYCLEVEN"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jedijedi re gbe wa lara re o si nyo o lenu nigbagbogbo. Ibe ni a npe ni "omusu" tabi iho idi enia ibiti a ma ngbe se igbonse. Arun Jedijedi je okan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Okunrin ti o si lagbara lati se iwosan re patapata.

Opolopo egbogi ni nwon nta kakiri ode nisisiyi ti won a ma polowo won fun iwosan re sugbon boya ni le ri mewa ninu ogorun ti o le se iwosan arun yi daradara. Awon elomiran lere wipeboya bi awon ba lo si ile Dokita lati lo ke eyiti o ba nyo jade lati omusu ku ni. pa be awon o bo lowo re palapata

Sugbon awa ko ro be rara: Lenin odun die lyonu re yio si tun ma bere bakanna, Orisirisi Jedijedi ni o wa ekini ti o bere nipa aiko ma se igbonse dede tabi lojojumo, elomiran nipa ijoko ni ojukanna selu lojojumo tabi gigun keke ylogere (Basikulu) pupo elomiran ewe nipa ije Suga tabi oniruru ohun adidun pupo ju. Jedijedi orisirisi ni o wa ewo ni tire? Bi o ba nyo jade ninu olusu tabi ti o ba nmu wa lehin igbonse tabi to ba i nyo ti o ba se igbonse tan ni, tabi ti nrin o nin musu ni eyikeyi ti o bara bere egboki "CYCLOVEN" ti awon Oyinbo Jamani fere wa idi re ko ki o si danwo orisi mela ni o dalu wipe iwo yio bo lowo Je li patapata alafia yio de si ekeji re ko si ninu gbogbo egbogi sa igboro ilu Naijiria Bere re ni:—

Waterloo Medecine Store

8, Palm Church Streer Lagos,

Phone 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)

## Ija Be Sile Larin Egbe Demo Ati UPGA Ni Ilesha

LESHA.—Ninu ija ... ti o be sile larin awon egbe oselu meji ti o wa ni Ipinle ... Oorun ni opin ose ti o koja yi nigbati awon omo egbe oselu kan lo ba awon obinrin ti nwon si nderu ba won pelu ... ki ni se ti won fi se omo egbe ... ti e fi nse omo egbe miran?

Nibiti nwon ti ... lowe ni awon omo egbe miran ba jade pelu ... kumo obe pelu ... fo igo ... ija ... a bere ni nwon ba bere si fa awon moto je ti awon ... ba awon ile ... awon oselu to wa ni Ilesha je ti nwon si ba moto okan ninu omo egbe Demo Olose B.bat... Olowo ... ti o je minista fun eto oun.

Nigbati awon Olopa yio fi de awon die ti salo ninu won awon meje pere ni nwon ri mu bayi.

Bena ... ileba Ilesha ni ilu kan ti o nje Ilewara ... awon ti ... ile omo egbe Demo kan je ... awon Olopa ti te enia meta mu ... ilu na baje.

Gbogbo enia ni o tun si ... ti nwon ko duro gb... ... kan ni ilu Ilesha nigbati awon kan ... ti oti emu ti awon be ... gbogbo igo akere... ati ile ti awon enia tio wa nibe ni.

Eniti ore ... se oju re se ... onkowe irohin ... ti ... Ilesha ... pe awon yi mu pelu ... nwon si ... awon Ol... egbe ose... miran kiri bi awon ti o ... ile oti emu yi ti ri ... gbogbo won ba fi ... ti olukuluku ti mu ... pon ... sa asala ... awon.

Ki awon Olopa to de, awon ti salo, awon Olopa ... nwon mu bayi.

## YE IRAWO RE WO

AQARIUS (Jan – Feb 20) Gegebi ojo ana beni ojo oni yio ri fun o ki o wa mura ... gbe ese siwaju, nipa ohunti o wa ninu okan re lati se, sugbon ore ni ki o ma ba gba gbogbo enia se.

PISCES (Feb – Mar 20) Ki o se suru, ninu ofi ati ola ... jeje ni ki o ma se ... ti buruku ... fun (e.e, mase loto ... pelu awon ti iwo pelu re ti nse gbogun si omi ko ... ri.

ARIES (Mar 21 – April 20) Suru ni ojo oni gba mase jeki ojo ... mu o ... ba ri itiseyin kekere kan, sa se suru, ki o fi ohun ti o ... o si ere, nipa ara re tabi awon ebi re.

TAURUS (April 21 – May 20) Ire mbe fun o loni ni gbogbo ... ti ... yio ma si losiwaju ninu ohun gbogbo, bi o ba ... gbogbo ... ti o mbe nile yio pari ...

GEMINI (May 21 – June 21) Ise gboyi lo mbe nile fun o loni, ... ki o mura si, bi o nte ki o ere nile, yan eyiti ... so pataki ti o si ... ki o si ... niso.

CANCER (June 22 – July 22) Awon enia to wa yio ka, yio ma o binu, sugbon ... ti o fi ara re je o y e Ma ... nise be, ... ko ... ti o ye ki o melo ti yio si ... siwaju.

LEO July 23 – Aug 22 ... kan ... si du pe lowo Olorun ... loni.

VIRGO Aug 23 – Sept 23 ... si ara re ngise lodi si ara won ... yio tisa yanju ara se ... ti yio fi ... lowo.

LIBRA Sept 24 – Oct 23 ... dara fun o lati lo sodo awon enia ... pipe yio si ...

SCORPIO Oct 23 – Nov 22 O ... ojo to gbadun la ti lo si ... ajo ...

SAGITTARIUS Nov 23 – Dec 21 Ise yio po fun o, ni ... sugbon ara re ... ise re ki die ki o si lo ... ara lele.

CAPRICORN Dec 22 – Jan 21 Ise re yio nitelorun ... ara ... tutu ... ara re ati ebi re.

## Iwo Ha Nfe Ile L'Eko Bi

| | |
|---|---|
| Room | £3 10/- |
| Room | £4 |
| Room | £5 |
| Room / Parlour | £6 |
| Room / Shop | £15 |
| Flat (Lagos) | £20 |
| Flat (E.B) | £25 |

Ti o ba nfe okan ninu awon ile wonyi yaa tete lo ri Ogbeni ODUS:— 187 Bamgbose Street Lagos ni deede agogo mejo irole si agogo meta irole. ijafara lewu anfani nla kan ni eyi je fun o pe o ri ile l'Eko

# Kereo Kere o Akiyesi Pataki




Awa na le jeri wipe Ojulowo ... Egbogi LEOPILLS awa na nlo ni Gold Coast (Ankara Ghana pelu meji re ko si ninu gbogbo orisirisi Egbogi ti o wa ni Ile Naijiria

A wa na ... ni igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lenu gbogbo enia tomode t'agba ni asiko yi ti nwon fi se oro ati orin larin ara won nipa Egbogi Jamani olokiki yi ti nwon npe ni LEOPILLS

Imoran awon Dokita Oyinbo ti nwon nse iwadi Egbogi LEOPILLS, yi kan so wipe bi o ti lagbara to ati bo je Ojulowo giriki ati atamatase fun "JEDIJEDI" bi o tiwu ki ojo re pe to ... ni nwon si tun fi owo soya tabi pe ile ... fun gbogbo awon ti ... tabi iju, Igbe sise, aiko ri igbonse deede, inurirun ... ara wiwo, Esan ... ehin didun ... ati aiko riran kedere ... buruku lara, aisan Onigbameji ati orisirisi aran miran gbogbo pelu

"Wipe nwon yio ri alafia ni kiakia ti nwon nba egbogi LEOPILLS nitoripe o tun matun eje se enia nipa ... ohun.

RANTI PE ALAFIA LOGUN ORO IJAFARA SI LEWU PELU.

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:— Igo nla ... meta abo (6/-6 pere Igo kekere ... meta abo (3/6) pere. Ber Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi A... ti e ba fe ... Sobu awon:—

WATERLOO MEDICINE STORE
8, Palm Church Street Phone 22787

NIGERIAN MEDICINE STORES ALOB
4, Tinubu Square Lagos
ATI NI SOBU
ISE OLODUMARE DISPENSARY OKE
IBADAN
ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba

# ADEGBENRO KI OLOYE AWOLỌWỌ KU ORIRE

Ni ọjọ ọjọ 'Bo ti iṣe ọjọ kẹdọgbọn oṣu yi ni iyawo olori ẹgbẹ Afẹnifẹre iyaafin oloye Hannah Awolọwọ ṣe ajọyọ ayajọ ọjọ ibi rẹ eyiti o fi di ẹni adọta ọdun ni ile aiye ti oloye na pẹlu awọn ọmọ rẹ, ọmọ ọmọ rẹ, iya ati awọn ọrẹ ba ṣe ayẹyẹ ọjọ ibi na ninu ile rẹ ni Ikẹnnẹ Ijẹbu Rẹmọ.



Alhaji D. S. Adegbenro
Adele olori egbe Afẹnifere

Ni ojo Aiku ti iṣe ojo kejid'nlogbon oṣu yi ni Iyaafin Hannah Awolowo yio lọ se idupẹ ajọyọ ayajọ ibi rẹ na ni Ile Ọlọruu ti Saint Sanihar Chnrch, Ikẹnne ni kutukutu owuro ojo ni. Nibi ayẹyẹ Isin idupe na ni oloye iyaafin Awolowo ylo ti fi Aga iwasu kan eyi ti nwon fi okuta iyebiye ṣo ta ile Ọlorun ti Ikẹnnẹ lorẹ.

Ninu iranṣẹ ikini ku ori re ti awon okeaimoye en a fi ranṣe si iyaafin Awolowo fun ti ojo ibi rẹ na ni Adele olori ẹgbẹ Afẹnifẹre ati olori egbẹ UPGA ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Alhaji D. S. Adegbenro ti ranṣẹ bayi pe, "Emi ati awon ẹbi mi ba o yo fun ti ajoyo ayajo ojo ibi rẹ eyiti o di ẹni adota odun ati pe mo tun ni adura si ọ pe ẹmi rẹ yio ṣe ọpọ rẹ"

Alhaji D S Adegbenro tun ṣe alaye ninu iranṣẹ ikini ku orire rẹ pe Nigbati o ti di ẹni adọta ọdun o dabi eni pe eni ọgbọn ọdun ni ọ. Alhaji D S Adegbenro tun ṣe alaye pe fun ọpọlọpọ iṣory ti o ti ri lati odud 1962 o si tun wa lẹ: hin oko re ati fun eto ofiu iṣelu eoiti iṣe fun ti anfani ati ilosiwaju awon e ia orile ede Naijiria.



Oloye Ọbafẹmi Awolowo
Olori ẹgbẹ Afenifẹre

Alhaji Adegbenro tun ṣe alaye pe loruko egbe Afenifere ti ile Naijiria "mo ba o yo fun ti ojo ibi re ati pe ni o ku orire fun ti ayajo ojo ibi re" "mo tun ki iwọ ati awon ebi re pe emi nyin yio ṣe opolopo re ni ile aiye"

Ninu eniti oranṣẹ ikini ki orire si Iyaafin oloye Awọlọwọ fun ti ọjọ ibi rẹ ni Alhaji A, L. A Adenikan tise ọmọ ẹgbẹ Afẹnifere ni ile Igbimọ Asofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ orun Naijiria

Ninu iranse ikini ku ori re ti Alhaji A L Adenikan fi ransẹ si oloye Awolowo ni o ti ṣe alaye pe loruko awon ẹgbẹ UPGA ni ilẹ Egba pe on ki Iyaafin Awolowo ku ori re ati pe adura awon ẹgbe UPGA ilẹ Ẹgba si Oloye Awolowo ni pe ki ẹmi rẹ si ṣe upolopọ rẹ.

Ni ojo ojo 'Bo ti iṣe ojo kẹdogbon oṣu yi ni Alhaji A L Adenẹkan si di ẹni ogoji odun laiye eyiti o jẹ wipe ojo na ni Alhaji na ṣe ojo ibi tirẹ bakanna,

## Lati Oju Ewe Keji

awon si tun wa bayi ni oni yi.

Bi o tilẹ jẹ wipe orilẹede awọn ti padanu awọn nkan ribiribi ri, gẹgẹbi orilẹ ede sugbọn loni yi, o so wipe awọn ti tun ni gbogbo awọn nkan ti awọn ti sonu ri won ni ilepo mẹrin tabi ju be le loni yi ti awọn ba wo ipo ti orile ede awọn wa ki ogun na to de ati bi ogun na si ti se ba orilẹ ede awọn jẹ to nigbana.

Nigbati awọn fi oju inu wo asiko na ti awọn wo ohunti ogun na ba jẹ mọ awọn lowo nigbana tiawọn si tun wo iru aye ti Ọlọrun tun wa gqe si ni oni yi, o ṣe wipe ọpọlọpọ opo le ye ki awọn maa du lọdọ Ọlọrun Oba ti ti o tun pese awọn nkan ti awọn ni gẹgẹ bi orilẹ ede loni fun awọn.

Asoju Ijẹba na tun se alaye ninu ọrọ rẹ wipe awọn Ile Ise tuntun tiawọn ti da sile lenu igbati ogun na ti pari jẹ eyiti inu awọn dun si lọpọlọpọ wipe awọn tun le ni iru rẹ pada.

O tun sọ pẹlu wipe bi enia ba de orilẹ ede Yugoslavia loni yi, ko si ẹniti o le mo ogun ti ja ilu na ri, a fi ẹniti o ba mọ igbana nikan lele ri, gbogbo awọn nkan na ni nwọn ti paha-bọ sipo lowọ ba wọnyi.

Ni ipari ọrọ rẹ, Ọlola Karapandza wa ra gbogbo awọn olotu Iwe Irohin wipe ki gbokho wọn jọwọ ki nwọn ma ṣe alaiko wa si ibi Iranti Ayaje Ominira ti awọn fẹ ṣe ni nomba 22 Alhaji Ribadu Road, Ikoyi.

Gẹgẹbi a ti ṣe siwaju tẹli ni deede agogo meje Irọlẹ loni ni ayẹyẹ na yio bẹrẹ nwọn yio si pari rẹ ni agogo mẹsan alẹ.

Oniṣe Irohin wa Ejo-ngboro yio lọ si ibiti nwọn yio gbe ṣe Iranti Ayajọ ajọyọ Ominira na ni alẹ loni gbogbo awọn ohuntl nwọn ba si ṣe nibẹ ni ẹ o mu gbọ ninu Iwe Irohin wa lalpẹ ati aworan gbogbo awọn enia sarakisaraki ti nwọn ba lọ sibi aṣeyẹ na,

# O Ti De Jaburata

Eyi n i lati kede fun awọnOnibara wa pe. Iwe Itumo Ala. I ṣ ẹ Wiwo, ọjọ ibi Ọmo de lati Oogun Ajẹbidan alapapo wa nilẹ fun tita nisisiyi, tete wa ra irẹ loni ki o to tan.

A s i tun ṣẹṣẹ ṣ e Iwe Itumo Ala miran ati owo Joseph Alala 9 Irohin ko to afojuba 3/6d pere ni, ẹyọ kan, mejila tabi dosin i rẹ jẹ 30/-

J. O. SHOYINKA
P. O. Box 159,
tabi 9, Iyala Street
Mushin.



Ọgbẹni J. O. Shoyinka

A s i nfẹ awon ti y'o ma ba wa ta awon iwe wa na
Tete wa si ọdọ Olotu
POPULAR PRINTING PRESS
9, Iyala Street, Mushin

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No 1,572 MONDAY NOVEMBER 29, 1965 (2D


## Baba Kan ati Omo Rẹ W'ẹwon Odun Meje

AKURẸ:- Ni ojo Abameta ti ise ojo ketadinlogbon osu yi ni Adajọ agba de ejo kekere ti ilu Akure iya afin Adunola Ogantoye pasẹ pe ki Ọkunrin agba kan David Ewere ti ise eni odun marundinlogota ati ọmọ rẹ Freeborn Ewere eni odun mejilelogun yara lo fi ẹwon ọdun meje jura fun ẹsun ole jija

Ninu idajọ Adajọ agba de ejo na ni oti pase pe ki baba David Ewere lo si ẹwon ọdun marun ati pe ki ọmo rẹ Freeborn Ewere lo si ẹwon odun meji

Ninu oro olopa to ba awon odaran omo ati baba se ni oti ṣe alaye fun ile ẹjọ na pe ni ogunjo osu kejo odun yi ni awon olosa na pelu awon enia miran ti awon olopa ko ri mu lo duro si oju ona Akurẹ si ona Ondo eyiti awon odaran na si fi gbe awon igi nla di oju ona lati mase jeki awon moto ri ona gba koja

Ọlopa to ba awon odaran na sẹjo tun se alaye pe nigbati moto akero kan de ibiti awon olosa na ti gbe igi nla di oju ona na ni awon ko le ri ona gba koja eyiti awon olosa na si fi kolu awon enia ti o wa ninu moto na ti nwon si gba owo ati ẹru awon enia to wa ninu moto na

### IWE IROHIN ILU OKERE SO PE :

# ỌNA ẸRU NI ẸGBẸ DẸMỌ GBA WỌLE NINU IBO

Ko si ẹniti yio ka iwe irohin kan ti njade ni ọsọsẹ ni ilu Amerika ti o njẹ Asiko (Time) ti oju koni ga a Oluwarẹ ti lori ọna ti o gba kọ bo ti nwọn di ni Ipinlẹ Iwọ Orun, nigbati o sọ gbogbo ona magomago ti nwọn fi dibo na, eyiti Ọkunrin fi nloyun iwe ibo ti nwọn nba iwe ibo ninu apo awọn Ọga to joko sibi ti nwọn ti ndibo ati bi awọn ti nlọ si Ibadan lati lọ so fun awọn aṣoju Oloye Akintọla lati sọ ẹniti o ba wole ninu awọn ọmọ ẹgbẹ ti nwọn dibo fun, Iwe na jade ni ọjọ kọkandinlogun oṣu yi.

Ọrọ inu iwe na sọ bayi "Nigbogbo igba ni awọn ọmọ ilẹ Naijiria ma lọ dibo ona kanna si ni nwọn nma gba dibo nwọn na, njẹ awon Imale Ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria ti nwon ju idaji enia to wa ni ilẹ Naijiria lo le maa joba le awon ti o ku lori ni'lẹ na ?

"Idahun kanna ti ko yato lo wa, Lona kan tabi lona miran lati igbati ilẹ Naijiria ti gba Ominira lati bi odun marun sẹhin ni Ipinlẹ Ariwa ti di ipo olori awon minista mu, ti won si pọ ju awọn Ipinlẹ toku lọ ninu Ile Igbimọ Aṣofin Apapọ Ijọba ti awon si di ipo nla mu pẹlu laisi ikunsinu nwọn paṣẹ le ipinlẹ toku lori.

Eyiti o wa jẹ ajoji ni o wa ni Ipinlẹ Iwọ Orun nibi ti Oloye Samuel Akintola ti o fi ara mọ Ijọba Ariwa ti o doju kọ atako ti o nipọn. Oloye Akintola ko ni enia ti o pọ lẹhin to di ala koso Ijoba Ipinlẹ Iwọ orun ni odun mẹta sẹhin lẹhin ti nwon fi Oloye Awolowo sẹwọn eniti ko faramọ Ijọba Ipinlẹ Ariwa.

Ṣugbon nigbati a ti dibo si Ipinlẹ Ariwa ku felefẹlẹ ni oṣu to lo ni oloye Akintola ... lati wa le ninu ibo na si iyalẹnu gbogbo enia a fi igbati o ṣe magomago ti nwọn fi ọna eru di ibo ni Ipinlẹ Iwọ Orun.

"Gbogbo awọn akowe ti yio fun nwọn ni iwe aṣẹ lati dibo fun awon UPGA ni nwọn gbe pamọ ti awọn ọmọ egbẹ UPGA ti nwọn yio dibo fun ko si mọ nkankan nipa iwe ibo na

"Awọn ibiti nwọn yio ti dibo fun ẹgbẹ Awolọwọ ni nwọn ko ri iwe idibo, awọn ogunna gbongbo ẹgbẹ Akintọla si tọju apoti iwe ibo bi nwọn ti fẹ

### ỌKUNRIN LOYUN IWE IBO

"Eyiti o wa ya enia lẹnu ni ti awọn ọkunrin ti o lọ loyun iwe idibo jaburata, ẹniti o nṣe akiyesi sọ pe, ni gbogbo agbegbe ti nwọn ti dibo ni nwọn ti ko gbogbo poti ibo wa si Ibadan lọ dọ asoju Akintola lati ka awọn iwe ibo, nigbati kika iwe ibo na si pari, eyiti a gbọ ti o ya ni lẹnu ni wipe, ẹgbẹ Dẹmọ ko aye ijoko mejidinlogorin (78) ẹgbẹ UPGA ko aye ijoko mejidinlogun 18 ... kan ninu awọn enia ti o ma sọrọ lori iṣẹlẹ Ọgbẹni Peter



Oloye S. L. Akintola
Olori Ẹgbẹ Dẹmọ

Enahoro sọ wipe, "Ipinlẹ Iwọ Orun ti lọ jinna.

"Sugbọn emi ko le sọ pato pe enia le sọ pẹlu otitọ pe ọna ti nwọn gba di ibo Ipinlẹ Iwọ Orun jẹ nkan tuntun lori ọna ti nwọn gba ndibo ni ilẹ Naijiria.

### IṢO NI AGBARA

"O tito yi oro pataki ko ti jade orisirisi nkan lo ti o ṣẹlẹ nibiti nwọn ti dibo ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria awọn Ohinrin ọlọja ko ta oja mọ lati lodi si abayọri ibo na ilu pupọ kori onjẹ jẹ mọ ija gboro ti o gba ẹmi enia marundinlogoji ni ilu kan soso awọn ilu miran di ẹẹru ni Abẹokuta nwọn kan iṣo mọ Adajọ kan ti o faramọ Hausa lori pẹlu akọwe ile ẹjọ na

Ohunti a gbọ sọ wipe ole ni adọrin enia ti nwọn tipa ole ni ẹgọrun enia ti owa ni Ile iwosan fun itọju larin ọsẹ mẹta ti nwon ti dibo tan Nwọn dojukọ ihalẹ awon ti nbinu si wọn ni ọsẹ ti o koja ni awon enia Ipinlẹ Ariwa nwa ifohunsokan Adajọ agba fun apapọ Ijọba Naijiria lọ si Ibadan lati lọ sọ agbara ki oloye Akintola le ni Ijẹba Apapọ labẹ Oloye Akintola

Fun awọn enia to wa lẹhin oloye Awo nwọn si to ọrọ na daada Sugbon aipa to yio san ju rara fẹ lo Ipinlẹ ti ko ba faramọ Ipinlẹ Ariwa dajudaju yio wa gbu nduku ni ẹkan ninu awọn ti o padanu aiye ninu ibo ti nwọn di koja wi ni ọsẹ ti o koja Bi oba tun le wa aipa alatako fun ọdun marun si ao di koto ti nwon nsin o u si


**Ẹma a ka Irohin Imolẹ Ki ẹsi maa Polowo Oja Nyin Sinu Rẹ Lojojumo**



Printed & Published by Modupe Printing Press 15, Bangbose Street, Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 45 Campbell Street Lagos. 29/11/65